**3.** Dajudaju ẹniti o nbinu rẹ ni gbogbo õre ti tan fun (ẹhin rẹ ti tan).

إِنَّ شَانِئَكَ هُوَ ٱلۡأَبۡتَرُ ٣

## (109) Suratul - Kãfirũna

## سُورَةُ الكَافِرُونَ

*Ni orukọ Ọlọhun Ajọkẹ aiye, Aşakẹ ọrun.*

بِسۡمِ ٱللَّهِ ٱلرَّحۡمَٰنِ ٱلرَّحِيمِ

**1.** Sọpe: Mope ẹnyin alaigbagbọ.

قُلۡ يَٰٓأَيُّهَا ٱلۡكَٰفِرُونَ ١

**2.** Emi kò ni sin ohun ti ẹ nsin.

لَآ أَعۡبُدُ مَا تَعۡبُدُونَ ٢

**3.** Atipe ẹnyin nã kò ni sin ohun ti emi nã nsin.

وَلَآ أَنتُمۡ عَٰبِدُونَ مَآ أَعۡبُدُ ٣

**4.** Atipe emi kò ni jẹ olujọsin ohun ti ẹ nsin.

وَلَآ أَنَا۠ عَابِدٞ مَّا عَبَدتُّمۡ ٤

**5.** Bẹ si ni ẹnyin kò ni jẹ olujọsin ohun ti emi nsin.

وَلَآ أَنتُمۡ عَٰبِدُونَ مَآ أَعۡبُدُ ٥

**6.** Ẹsin (aigbagbọ) ti nyin wà fun nyin, ẹsin (igba-Ọlọhun-lọkan) temi si wà fun mi.

لَكُمۡ دِينُكُمۡ وَلِيَ دِينِ ٦

## (110) Suratul - Nasri

## سُورَةُ النَّصۡرِ

*Ni orukọ Ọlọhun Ajọkẹ aiye, Aşakẹ ọrun.*

بِسۡمِ ٱللَّهِ ٱلرَّحۡمَٰنِ ٱلرَّحِيمِ

**1.** Nigbati aranşe Ọlọhun ba de ati işẹgun.

إِذَا جَآءَ نَصۡرُ ٱللَّهِ وَٱلۡفَتۡحُ ١

**2.** Atipe irẹ yio ri awọn enia ti nwọn yio mã wọ inu ẹsin ti Ọlọhun nijọ-nijọ.

وَرَأَيۡتَ ٱلنَّاسَ يَدۡخُلُونَ فِي دِينِ ٱللَّهِ
أَفۡوَاجٗا ٢